28. Awọn ọmọ rẹ̀ dide, wọn si pe e ni alabukun-fun, ati baale rẹ̀ pẹlu, oun si fi iyin fun un.

29. "Ọpọlọpọ awọn ọmọbinrin ni o huwa rere, ṣugbọn iwọ ta gbogbo wọn yọ!" (Owe 12:4.)

30. Ojú daradara ni ẹ̀tàn, ẹwa si jasi asán: ṣugbọn obinrin ti o bẹru Oluwa, oun ni ki a fi iyin fun. (Owe 6:25; 22:4.)

31. Fi fun un ninu èso-iṣẹ ọwọ́ rẹ̀; jẹ ki iṣẹ ọwọ́ rẹ̀ yìn ín ní ẹnubode.

21

# IWE ONIWAASU

**(B.C. 977)**

ORI 1.

**Asán ni làálàá eniyan.**

ỌRỌ oniwaasu, ọmọ Dafidi, ti o jọba ni Jerusalẹmu. (ẹsẹ 12; Onws 7:27; 12:8–10.)

2. Asán ninu asán, oniwaasu naa wi pe, asán ninu asán; gbogbo rẹ asán ni! (Psm 39:5,6; 62:9; 144:4; Onws 12:8.)

3. Èrè kinni eniyan jẹ ninu gbogbo làálàá rẹ̀ ti o ṣe lábẹ́ ọrun? (Onws 2:22; 3:9.)

**Iran kan nlọ iran kan nbọ.**

4. Iran kan nlọ, iran miran si nbọ̀: ṣugbọn ayé duro titi lae. (Psm 104:5; 119:90.)

5. Òòrùn pẹlu là, òòrùn si wọ̀, o si yara lọ si ipo rẹ̀ nibi ti o ti là. (Psm 19:5,6.)

6. Afẹfẹ nfẹ lọ sihà gusù, o si yipada siha ariwa; o si nlọ sihin sọhun titi, afẹfẹ si tun pada gẹgẹ nipa ayika rẹ̀. (Onws 11:5; Jhn 3:8.)

7. Odò gbogbo ni nṣan sinu òkun; ṣugbọn òkun kò kún nibi ti awọn odò ti nṣan wa, nibẹ ni wọn si tun pada lọ.

8. Ohun gbogbo kun fun ààrẹ̀; eniyan kò lè sọ ọ: iran ki i sú oju, bẹẹ ni eti ki i kún fún gbigbọ. (Owe 27:20.)

9. Ohun ti o wà, oun ni yoo si wà; ati eyi ti a ti ṣe ni èyí ti a o ṣe; kò si ohun titun labẹ òòrùn. (Onws 2:12; 3:15.)

10. Ohun kan wa nipa eyi ti a wi pe, "Wo o, titun ni èyí!" o ti wà naa nigba atijọ, ti o ti wà ṣaaju wa.

11. Kò si iranti ohun iṣaaju; bẹẹ ni iranti ki yoo si fun ohun ikẹhin ti nbọ wa ṣelẹ̀ lọdọ awọn ti nbọ nigba ikẹhin. (Onws 2:16; 9:5.)

**Asán ni ọgbọn eniyan.**

12. Emi oniwaasu jọba lori Israẹli ni Jerusalẹmu. (ẹsẹ 1.)

13. Mo sì fi àyà mi si ṣiṣe afẹri ati iwadi nipa ọgbọn ohun gbogbo ti a nṣe labẹ ọrun, làálàá kikan yii ni Ọlọrun fi fun awọn ọmọ eniyan lati ṣe làálàá ninu rẹ̀. (ẹsẹ 17; Onws 3:10.)

14. Mo ti ri iṣẹ gbogbo ti a nṣe labẹ òòrùn; si kiyesi i, asán ni gbogbo rẹ ati ìmúlẹ̀mófo. (Onws 2:11,17.)

15. Èyí ti o wọ́, a ko le mu un tọ́: ati ẹ̀yí ti o lábùkù, a kò lè ka a. (Onws 7:13.)

16. Mo si ba àyà mi sọrọ wi pe, "Kiyesi i, mo ni ọgbọn nla, àní ju gbogbo wọn lọ ti o ti ṣaaju mi ni Jerusalẹmu; àyà mi si ri ohun pupọ nla ti ọgbọn ati ti ìmọ̀." (1 A.Ọba 3:12,13; 4:30; 10:23; Onws 2:9.)

17. Nigba ti mo fi àyà mi si mimọ ọgbọn, ati lati mọ isínwin ati iṣe-òmùgọ̀: nigba naa ni mo mọ̀ pe, eyi pẹlu jẹ imulẹmofo. (Onws 2:3,12; 7:23,25.)

18. Nitori pe ninu ọgbọn pupọ ni ibanujẹ pupọ wà, ẹni ti o si nsọ ìmọ̀ di pupọ, o nsọ ikaanu di pupọ. (Onws 12:12.)

## ORI 2.

**Asán ni afẹ́ ati ọrọ̀.**

EMI wi ninu mi pe, "Wá ná! emi o fi ire-ayọ̀ dan ọ wò, nitori naa maa jẹ afẹ́!" si kiyesi i, asán ni èyí pẹlu! (Luk 12:19; Onws 1:2.)

2. Emi wi fun ẹ̀rín pe, "Wèrè ni." ati fun iré-ayọ̀ pe, "Iṣẹ́ kinni o ṣe?" (Owe 14:13; Onws 7:6.)

3. Mo rò ninu àyà mi lati fi oti-waini mu ara mi le, ṣugbọn emi nfi ọgbọ́n tọ́ àyà mi: lati fi ọwọ́ le ìṣe-òmùgọ̀, titi emi o fi ri ohun ti o dara fun ọmọ eniyan, ti wọn iba maa ṣe labẹ ọ̀run ni iye ọjọ́ ayé wọn gbogbo.

4. Mo ṣe iṣẹ́ nla fun ara mi; mo kọ́ ile pupọ fun ara mi; mo gbin ọgba-àjàrà fun ara mi. (1 A.Ọba 7:1–12; O.Sol. 8:10,11.)

5. Mo ṣe ọgba ati àgbàlá daradara fun ara mi, mo si gbin igi oniruuru èso sinu wọn. (O.Sol. 4:16; 5:1; Neh 2:8.)

6. Mo ṣe adagun pupọ, lati maa bomi lati inu wọn si igbo ti o nmu igi jade wá;

7. Mo ni ìránṣẹ́kùnrin ati ìránṣẹ́bìnrin, ati iranṣẹ ti a tilẹ̀ bi ninu ile mi; mo si ni ohun iní agbo malu ati àgùtàn nlanla ju gbogbo awọn ti o wa ni Jerusalẹmu ṣaaju mi.

8. Mo si ko fadaka ati wura jọ ati iṣura ti ọba ati ti ìgbèríko, mo ni awọn olorin ọkunrin ati olorin obinrin, ati ohun-idunnu fun ọmọ eniyan, àní aya ati obinrin pupọ. (1 A.Ọba 9:28; 10:10,14,21; 4:21; 20:14; 2 Sam 19:35.)

9. Bẹẹ ni mo tobi, mo si pọ̀ si i ju gbogbo awọn ti o wà ṣaaju mi ni Jerusalẹmu: ọgbọ́n mi si nbẹ pẹ̀lú mi. (Onws 1:16.)

10. Ohunkohun ti oju mi fẹ, emi kò pa a mọ fun wọn; emi kò si du àyà mi ni ohun ayọ̀ kan; nitori ti àyà mi yọ̀ ninu iṣẹ́ mi gbogbo; èyí si ni ipin mi lati inu gbogbo làálàá mi. (Onws 3:22; 5:18; 9:9.)

11. Nigba ti mo wo gbogbo iṣẹ́ ti ọwọ́ mi ṣe, ati làálàá ti mo ṣe wahala lati ṣe: si kiyesi i, asán ni gbogbo rẹ ati imulẹmofo, ko si si ere kan labẹ ọ̀orun. (Onws 1:3,14.)

**Ati omugọ ati ọlọgbọn ni yoo ku.**

12. Mo si yi ara mi pada lati wo ọgbọ́n, ati ìsínwín ati ìṣe-òmùgọ̀: nitori pe kinni ọkunrin naa ti nbọ lẹ́hìn ọba yoo le ṣe? Afi èyí ti a ti ṣe tan ni yoo ṣe. (Onws 1:17; 7:25.)

13. Nigba naa ni mo ri pe ọgbọn ta wèrè yọ, to iwọn bi imọlẹ ti ta okùnkùn yọ. (Onws 7:11,12.)

14. Oju ọlọgbọn nbẹ ni ori rẹ̀: ṣugbọn omugọ nrin ni òkùnkùn: emi si mọ̀ pẹlu pe, abayọri kannaa ni gbogbo wọn. (Owe 17:24; Psm 49:10; Onws 9:2,3,11.)

15. Nigba naa ni mo wi ni àyà mi pe, Bí o ti nṣe aṣiwere, bẹẹ ni o ṣe nṣe si emi tikalarami; nitori kinni emi si ṣe gbọn jù? Nigba naa ni mo wi ni ọkan mi pe, asán ni èyí pẹlu. (Onws 6:8,11.)

16. Nitori pe iranti kò sí fun ọlọgbọn pẹlu omugọ laelae; ki a wo o pe, bi akókò ti o kọja, bẹẹ ní ọjọ ti nbọ, a o gbagbe gbogbo rẹ̀. Ọlọgbọn ha ṣe nku bi òmùgọ̀! (Onws 1:11; 9:5; ẹsẹ 14.)

17. Nitori naa mo korira ìwàláàyè; nitori pe iṣẹ ti a ṣe labẹ ọ̀ọ̀rùn: ibi ni fun mi: nitori pe asán ni gbogbo rẹ̀ ati ìmúlẹ̀mófo. (Onws 4:2; ẹsẹ 22:23.)

**Ikojọ-ọrọ̀ eniyan ni yoo fi silẹ fun ẹlomiran.**

18. Nitootọ mo korira gbogbo laalaa mi ti mo ṣe labẹ ọ̀ọ̀rùn: nitori ti emi o fi i silẹ fun eniyan ti nbọ lẹ́hìn mi. (ẹsẹ 11; Psm 39:6; 49:10.)

19. Tani o si mọ bi ọlọgbọn ni yoo ṣe tabi aṣiwèrè? Sibẹ oun ni yoo ṣe olori iṣẹ mi gbogbo ninu èyí ti mo ṣe laalaa, ati ninu èyí ti mo fi ara mi hàn ni ọlọgbọn labẹ ọ̀ọ̀rùn, Asán ni èyí pẹlu.

20. Nitori naa mo kiri lọ lati mu àyà mi ṣí kuro ninu gbogbo làálàá mi ti mo ṣe labẹ ọ̀ọ̀rùn. (ẹsẹ 11.)

21. Nitori ti eniyan kan nbẹ, iṣẹ ẹni ti o wa ni ọgbọ́n ati ni ìmọ̀, ati ni iṣedeede; ṣibẹ ẹni ti kò ṣe làálàá ninu rẹ̀ ni yoo fi i silẹ fún ni ìpín rẹ̀. Èyí pẹlu asán ni ati ibi nlánlà. (Onws 4:4; ẹsẹ 18.)

22. Nitori pé kinni eniyan ní ninu gbogbo làálàá rẹ̀ ti o fi nṣe làálàá labẹ òòrùn? (Onws 1:3; 3:9.)

23. Nitori pé ọjọ rẹ̀ gbogbo, ikaanu ni, ati iṣẹ rẹ̀, ibanujẹ, nitootọ àyà rẹ̀ kò simmi ni òru. Eyi pẹlu asán ni. (Job 5:7; 14:1; Onws 1:18; Psm 127:2.)

**Eniyan Ọlọrun yoo ni itẹlọrun ninu ohun ti Ọlọrun ṣe fún un.**

24. Kò sí ohun ti o dara fún eniyan ju ki o jẹ ki o sì mu ati ki o mu ọkàn rẹ̀ jadùn ohun rere ninu làálàá rẹ̀. Èyí ni mo ri pẹlu pe, lati ọwọ Ọlọrun wa ni. (Onws 3:12,13,22; 5:18; 8:15.)

25. Nitori pe tani o le jẹun, tabi tani pẹlu ti o le mọ adùn jù mi lọ?

26. Nitori pe Ọlọrun fun eniyan ti o tọ́ ní oju rẹ̀ ni ọgbọ́n, ati ìmọ̀ ati ayọ̀: ṣugbọn ẹlẹṣẹ ni o fi ìṣẹ́ fun, lati maa kó jọ ati lati maa tò jọ ki oun lè maa fi fun ẹni rere niwaju Ọlọrun. Èyí pẹlu asán ni ati ìmúlẹ̀mófo. (Job 32:8; 27:16,17; Onws 1:14.)

## ORI 3.

**Ohunkohun ni àkókò wa fun.**

OLUKULUKU ohun ní àkókò wa fun, ati igba fun iṣẹ gbogbo labẹ ọrun. (ẹsẹ 17; Onws 8:6.)

2. Ìgbà bíbíni, ati ìgbà kíku, ìgbà gbínbìn ati ìgbà kíká ohun ti a gbin; (Heb 9:27.)

3. Ìgbà pípa ati ìgbà imularada; ìgbà wíwó lulẹ̀ ati ìgbà kíkọ́;

4. Ìgbà sisọkun ati igba rirẹrin; ìgbà ṣiṣọ̀fọ̀ ati igba jíjó; (Rom 12:15; Psm 126:2; Eks 15:20.)

5. Ìgbà kíkó okuta dànù, ati ìgbà kíkó okuta jọ; ìgbà fifọwọkóni mọ́ra, ati ìgbà fífàsẹ́hìn ni fifọwọkóni mọ́ra; (1 Kor 7:5.)

6. Ìgbà wíwárí, ati ìgbà sísọnù; ìgbà pípamọ́ ati ìgbà ṣíṣátì;

7. Igbà fífàya, ati ìgbà rírán; ìgbà didakẹ, ati ìgbà fífọhùn; (Amos 5:13.)

8. Ìgbà lati fẹ́, ati ìgbà lati korira; ìgbà ogun, ati ìgbà alaafia. (Luk 14:26.)

9. Erè kinni o wà fún òṣìṣẹ́ ninu làálàá iṣẹ rẹ̀? (Onws 1:3.)

**Làálàá eniyan asán ni.**

10. Mo ti ri iṣẹ ti Ọlọrun fi fun awọn ọmọ eniyan lati maa ṣiṣẹ ninu rẹ̀. (Onws 1:13.)

11. O ti ṣe ohun gbogbo daradara nigba tirẹ; pẹlupẹlu o fi ayérayé si wọn ni àyà, bẹẹ ni ẹnikan kò lè ridi iṣẹ naa ti Ọlọrun nṣe lati ìpilẹ̀ṣẹ̀ titi de opin. (Gen 1:31; Onws 8:17; Rom 11:33.)

12. Emi mọ̀ pe kò si rere ninu wọn, bikoṣe ki eniyan maa yọ, ki o si maa ṣe rere ni igbéayé rẹ̀.

13. Ati pẹlu ki olúkúlùkù eniyan maa jẹ, ki o si maa mu, ki o si maa jadùn gbogbo làálàá rẹ̀, ẹbun Ọlọrun ni. (Onws 2:24; 5:19.)

14. Emi mọ pe ohunkohun ti Ọlọrun ṣe yoo wa laelae: a kò lè fi ohun kan kun un, bẹẹ ni a kò lè mu ohun kan kuro ninu rẹ̀; Ọlọrun si ṣe eyi ki eniyan lè maa bẹru rẹ̀. (Jms 1:17; Onws 5:7; 1:3; 3:9.)

15. Ohun ti o ti wà ri nbẹ nisinsinyìí, ati eyi ti yoo si wà, o ti wà ná; Ọlọrun si nwa èyí ti o ti kọja lọ. (Onws 1:9; 6:10.)

**Ọlọrun yoo ṣe idajọ rere ati buburu.**

16. Ati pẹlupẹlu mo ri ibi idajọ labẹ òòrùn pe iwa buburu nbẹ nibẹ; ati ni ibi ododo, pe aiṣedeede nbẹ nibẹ.

17. Mo wi ni àyà mi pé, Ọlọrun yoo ṣe idajọ olododo ati eniyan buburu nitori pé ìgbà kan nbẹ fun ohun gbogbo ati fun iṣẹ gbogbo. (Matt 16:27; Rom 2:6–8; 2 Kor 5:10; 2 Tess 1:6,7; ẹsẹ 1.)

18. Mo wi ni àyà mi ni ti ìwà awọn ọmọ eniyan; pé Ọlọrun ndan wọn wò lati fi hàn wọ́n, ati ki wọn lè ri pe ẹranko ni awọn tikarawọn jẹ́.

19. Nitori pé ohun ti nṣe ọmọ

eniyan nṣe ẹranko; àní ohun kannaa ni o nṣe wọn: bi ekinni ti nku bẹẹ ni ekeji nku; nitootọ ẹmi kannaa ni gbogbo wọn ni, bẹẹ ni eniyan kò ni ọlá ju ẹranko lọ: nitori pe asán ni gbogbo rẹ̀. (Psm 73:22; Onws 9:12.)

20. Nibikan naa ni gbogbo wọn nlọ; lati inú erupẹ wá ni gbogbo wọn, gbogbo wọn si tun pada di erùpẹ̀. (Gen 3:19; Onws 12:7.)

21. Tani o mọ ẹ̀mí ọmọ eniyan ti ngoke si apa òkè, ẹ̀mí ẹran ti nsọkalẹ si isalẹ ilẹ̀? (Onws 12:7.)

22. Nitori naa mo woye pé kò si ohun ti o dara jù ki eniyan maa yọ̀ ni iṣẹ ara rẹ̀; nitori èyiyii ni ipin rẹ̀: nitori pé tani yoo mu un pada wa ri ohun ti yoo wà lẹ́hìn rẹ̀. (Onws 2:24; 5:18; 6:12; 8:7; 10:14.)

## ORI 4.

**Adanilóró fi agbara kọni.**

BẸẸ ni mo pada, mo si ro inilára gbogbo ti a nṣe labẹ oorun; mo si wo omije awọn ti a nnilara, wọn kò si ni olùtùnú; ati lọwọ aninilara wọn ni ipa wa; ṣugbọn wọn kò ni olùtùnú. (Onws 3:16; 5:8; Isa 5:7; E.Jer. 1:9.)

2. Nitori naa mo yin òkú ti o ti ku ju awọn alààyè ti o wa láàyè sibẹ. (Job 3:11–26; Onws 2:17.)

3. Nitootọ, ẹni ti koi ti i sí sàn ju awọn mejeji; ẹni ti koi ti i ri iṣẹ buburu ti a nṣe labẹ òòrùn. (Onws 6:3.)

**Ilara ẹnikini lati ọdọ ẹnikeji rẹ̀.**

4. Ati pẹlu, mo ro gbogbo làálàá ati ìmọ̀ iṣẹ gbogbo, pe, eyiyii ni ilara ẹnikini lati ọdọ ẹnikeji rẹ̀. Asán ni èyí pẹ̀lú ati imulẹmofo. (Onws 2:21; 1:14.)

5. Aṣiwere fọwọ-lọwọ, o si njẹ ẹran-ara rẹ̀. (Owe 6:10; Isa 9:20.)

6. Ounjẹ ikunwọ kan pẹlu idakẹjẹ, o sàn ju ikunwọ meji lọ ti o kun fun làálàá ati imulẹmofo. (Owe 15:16,17; 16:8.)

7. Nigba naa ni mo pada, mo si ri asán labẹ òòrùn.

8. Ẹni kanṣoṣo wà, kò si ní ẹnikeji; nitootọ kò ni ọmọ, bẹẹ ni kò ni arakunrin sibẹ kò si òpin ninu làálàá rẹ̀ gbogbo; bẹẹ ni ọrọ̀ kò tẹ́ oju rẹ̀ lọ́rùn: bẹẹ ni kò si wi pe, "Nitori tani emi nṣe làálàá, ti mo si nfi ire du ọkàn mi?" Eyi pẹlu asán ni ati iṣẹ òṣì. (Owe 27:20; 1 Jhn 2:16.)

9. Ẹni meji sàn ju ẹnikan; nitori wọn ni èrè rere fun laalaa wọn.

10. Nitori pé bi wọn ba ṣubu, ẹnikini yoo gbe ẹnikeji rẹ̀ dide: ṣùgbọn ègbé ni fun ẹni ti o ṣe oun nikan nigba ti o ba ṣubu; ti kò ni ẹlomiran ti yoo gbe e dide.

11. Ati pẹlu, bi ẹni meji ba dubulẹ pọ̀, nigba naa ni wọn o mooru: ṣugbọn ẹnikan yoo ha ti ṣe mooru? (1 A.Ọba 1:1.)

12. Bi o tilẹ jẹ pé ẹnikan lè dá kọlu ẹnikan, ti o dá wà ẹni meji yoo lè ko o loju: Okun onişẹpo mẹta ki i ja bọ̀rọ̀.

**Otoşi ọ̀dọ́ ti o ṣe ọlọgbọn.**

13. Otoşi ọ̀dọ́ ti o ṣe ọlọgbọn, o sàn ju arúgbó ati omugọ ọba lọ ti kò mọ bi a ti ngba imọran. (Onws 9:15.)

14. Bi o tilẹjẹ pé lati inu túbú ni o ti jade wa jọba; tabi bi a ti lẹ̀ ti bi i ni talaka ninu ijọba rẹ̀. (Gen 41:14,41–43.)

15. Mo ri gbogbo alààyè ti nrìn labẹ òòrùn, pẹlu ọ̀dọ́ keji ti yoo dide duro ni ipo rẹ̀.

16. Ko si òpin gbogbo awọn eniyan; oun wà ṣaaju gbogbo wọn: sibẹ awọn pẹlu ti nbọ lẹ́hìn ki yoo ni ayọ̀ ninu rẹ̀. Nitootọ asán ni èyí pẹlu ati ìmúlẹ̀mófo. (Onws 1:14.)

## ORI 5.

**Mura lati gbọ ju lati ṣe irubọ asán.**

PA ẹsẹ̀ rẹ mọ́ nigba ti iwọ ba nlọ si ile Ọlọrun, ki iwọ si mura lati gbọ ju lati ṣe irubọ aṣiwere: nitori ti wọn kò mọ̀ pe wọn nṣe ibi. (Eks 3:5; Isa 1:12; 1 Sam 15:22; Owe 15:8; 21–27; Hos 6:6.)

2. Máṣe fi ẹnu rẹ yara, má ṣe jẹ ki

àyà rẹ yara sọ ọ̀rọ̀ niwaju Ọlọrun: nitori ti Ọlọrun nbẹ ni ọrun, iwọ si nbẹ ni ayé: nitori naa jẹ́ kí ọ̀rọ̀ rẹ mọ ni ìwọ̀n. (Owe 20:25; 10:19; Matt 6:7.)

3. Nitori pe nipa ọpọlọpọ iṣẹ ni àlá ti wa; bẹẹ ni nipa ọpọlọpọ ọ̀rọ̀ ni a nmọ ohùn aṣiwere.

4. Nigba ti iwọ ba jẹ ẹ̀jẹ́ fun Ọlọrun, máṣe duro pẹ lati san an: nitori kò ni inú-dídùn si aṣiwere: san èyí ti iwọ jẹ́jẹ̀ẹ́. (Deut 23:21–23; Psm 50:14; 76:11; 66:13,14.)

5. O sàn ki iwọ má jẹ ẹ̀jẹ́, ju ki iwọ jẹ́ ẹ̀jẹ́, ki o má san an. (Owe 20:25; A.A. 5:4.)

6. Máṣe jẹ ki ẹnu rẹ mu ara rẹ ṣẹ̀: ki iwọ má si ṣe wi niwaju iranṣẹ Ọlọrun pé, èṣì ni o ṣe: nitori kinni Ọlọrun yoo ṣe binu si ohùn rẹ, a si ba iṣẹ ọwọ́ rẹ jẹ́?

7. Nitori pé ninu ọpọlọpọ àlá ni asán wà, bẹẹ ni iparun wà ninu ọpọlọpọ ọ̀rọ̀ pẹ̀lú: ṣugbọn iwọ bẹru Ọlọrun. (Onws 3:14; 12:13.)

**Ojú-kokoro ati ọrọ̀ aiṣododo nyọri si ibi.**

8. Bi iwọ ba ri inilara awọn olupọnju, ati fifi agbara yí idajọ ati otitọ pada ni ìgbèríko, máṣe jẹ ki ẹnu o yà ọ́ si ọ̀ràn naa, nitori pé ẹni ti o ga ju nṣọ́ ẹni ti o ga, ati ẹni-giga-julọ wa lori wọn. (Onws 4:1; Psm 12:5; 58:11; 82:1.)

9. Pẹlupẹlu èrè ilẹ̀ ni fun gbogbo eniyan: a si nsin ọba tikararẹ paapa lati inu oko wá.

10. Ẹni ti o ba fẹ fàdákà, fàdákà ki yoo tẹ ẹ lọ́rùn; bẹẹ ni ẹni ti o fẹ ọrọ̀ ki yoo tẹ ẹ lọ́rùn: asán ni èyí pẹ̀lú. (Onws 2:10,11.)

11. Nigba ti ẹrù ba npọ si i, awọn ti o njẹ ẹ a maa pọ̀ si i: èrè kinni fun ẹni ti o ni i, bikòṣe pé ki wọn maa fi ojú rẹ̀ wò wọ́n? (Onws 2:9.)

12. Dídùn ni orun oniṣẹ, iba jẹ ounjẹ diẹ tabi pupọ: ṣugbọn itẹlọrun ọlọrọ kìí jẹ ki o sùn. (Owe 3:24.)

13. Ibi buburu kan nbẹ ti mo ri labẹ òòrùn, eyi ni pe, ọrọ̀ ni a npamọ fun ifarapa awọn ti o ni i. (Onws 6:1,2.)

14. Nitori ọrọ̀ wọnyìí yoo ṣegbe nipa idawọle buburu; o si jẹ baba ọmọkunrin kan, ṣugbọn kò si nkankan mọ́ lọwọ rẹ̀ (ti yoo fi tọju rẹ̀).

15. Bi o ti ti inu ìyá rẹ̀ jade wá, ihoho ni yoo si tun pada lọ bi o ti wá, ki yoo si mu nkan ninu làálàá rẹ̀, ti iba mu lọ lọwọ rẹ̀. (Job 1:21; Psm 49:17; 1 Tim 6:7.)

16. Ibi buburu ni èyí pẹ̀lú, pe ni ọ̀nà gbogbo, bi o ti wá, bẹẹ ni yoo si lọ: èrè ki si ni fun ẹni ti nṣe làálàá fun afẹ́fẹ́? (Onws 1:3; Owe 11:29.)

17. Ni ọjọ rẹ̀ gbogbo pẹ̀lú, o njẹun ni òkùnkùn, o si ni ibanujẹ pupọ ati àrùn ati irora. (Onws 2:23.)

**Nini ọrọ̀ ati jijẹ ninu rẹ ẹ̀bùn Ọlọrun ni.**

18. Kiyesi i, èyí ti mo ri ti o si yẹ fun eniyan ni ki o jẹ, ki o sì mu, ki o si maa jẹ alaafia ninu gbogbo làálàá rẹ̀ ti o ṣe labẹ òòrùn, ni iye ọjọ ayé rẹ̀ gbogbo, ti Ọlọrun fi fun un: nitori èyí ni ipin tirẹ. (Onws 2:10,24; 3:22.)

19. Bi Ọlọrun ba fi ọrọ̀ fun ẹnikẹni, ti o si fun un ni agbara ati jẹ ninu rẹ̀: ati lati mú ìpín rẹ̀, ati lati yọ̀ ninu laalaa rẹ̀; èyí pẹlu ẹ̀bùn Ọlọrun ni. (2 Kro 1:12; Onws 2:24; 3:13; 6:2.)

20. Nitori ti ki yoo ranti ọjọ́ ayé rẹ pupọju; nitori ti Ọlọrun da a lóhùn ninu ayọ̀ ọkàn rẹ̀.

## ORI 6.

**Ọrọ̀ ati ọlá, laini Ọlọrun, jásí asán.**

IBI kan nbẹ ti mo ri labẹ òòrùn, o si ṣọpọ laarin awọn ọmọ eniyan. (Onws 5:13.)

2. Ẹni ti Ọlọrun fi ọ̀rọ̀, ọlá ati ọlà fun, ti kò si si nkan ti o kù fun ọkàn rẹ̀, ninu ohun gbogbo ti o fẹ, ṣugbọn ti Ọlọrun ko fun un ni agbara lati jẹ ninu rẹ, ṣugbọn awọn ajeji eniyan ni o njẹ ẹ: asán ni èyí, arun buburu si ni. (1 A.Ọba 3:13; Psm 17:14; 73:7.)

3. Bi ọkunrin kan bi ọgọrun ọmọ, ti o si wà ni ọdún pupọ, tobẹẹ ti ọjọ

ọdún rẹ̀ pọ̀, ti ọkàn rẹ̀ kò si kun fun ohun didara, ati pẹlu ti a kò si sinku rẹ̀; mo ni, ọmọ ìṣẹ́nù san ju u lọ. (2 A.Ọba 9:35; Isa 14:19,20; Jer 22:19; Onws 4:3.)

4. Nitori pe lásán ni o wà, o si lọ ni ọkunrin, òkùnkùn ni a o si fi bo orukọ rẹ̀ mọlẹ.

5. Pẹlupẹlu oun kò ri òòrùn kò mọ ohun kan: èyí ní isinmi ju ekeji lọ.

6. Ani bi o tilẹ wà ni ẹgbẹrun ọdún lọna-meji, ṣugbọn kò ri rere: ibikan-naa ha kọ ni gbogbo wọn nrè?

7. Gbogbo laalaa eniyan ni fun ẹnu rẹ̀, ṣugbọn a koi ti tẹ adùn ọkan rẹ̀ lọrun. (Owe 16:26.)

8. Nitori pe èrè kinni ọlọgbọn ní ju aṣiwere lọ? Kinni talaka ní ti o mọ̀ bi a ti rìn niwaju awọn àlàáyè? (Onws 2:15.)

9. Eyi ti ojú rí sàn ju iwakiri – ifẹ ọkàn lọ; asán ni eyi pẹlu ati imulẹmofo. (Onws 11:9; 1:14.)

10. Eyi ti o wà, a ti da orukọ rẹ̀ rí, a si ti mọ ọ pe, eniyan ni: bẹẹ ni kò lè ba ẹni ti o lagbara ju u lọ jà. (Onws 1:9; Job 9:32; Isa 45:9; Jer 49:19.)

11. Kiyesi i, ohun pupọ ni o wa ti nmu asán bí si i, èrè kinni eniyan ní?

12. Nitori pé tani o mọ ohun ti o dara fun eniyan ni ayé yìí, ni iye ọjọ asán rẹ̀ ti nlọ bi ojiji? Nitori pé tani o lè sọ fun eniyan kinni ohun ti yoo wà lẹ́hìn rẹ labẹ òòrùn? (Jms 4:14; Psm 39:6; Onws 8:7.)

ORI 7.

**Onigbagbọ ni lati lepa àti ṣe rere ju àti ṣe buburu lọ.**

ORUKỌ rere dara ju òróró ikunra; ati ọjọ ikú ju ọjọ ìbí eniyan lọ. (Owe 15:30; 22:1; Onws 4:2.)

2. O dara lati lọ si ile ọ̀fọ̀ ju lati lọ si ile àsè: nitori pé eyi ni opin gbogbo eniyan; alààyè yoo si pa a mọ ni àyà rẹ̀. (Onws 2:16; Psm 90:12.)

3. Ibanujẹ sàn ju ẹ̀rín: nitori pe nipa ìfàro ojú a si mu àyà dunnú. (2 Kor 7:10.)

4. Àyà ọlọgbọn nbẹ ni ilé ọ̀fọ̀; ṣugbọn àyà aṣiwere nbẹ ni ile ayọ̀.

5. O sàn lati gbọ́ ibawi ọlọgbọn ju ki eniyan fetí si orin aṣiwere. (Psm 141:5; Owe 13:18; 15:31,32.)

6. Nitori pe bi ìtapàpà ẹ̀gún labẹ ìkòkò, bẹẹ ni ẹ̀rín aṣiwere: asán ni èyí pẹ̀lú. (Psm 118:12; Onws 2:2.)

7. Nitootọ inilara mu ọlọgbọn eniyan sinwin; ọrẹ a si ba àyà jẹ́. (Eks 23:8; Deut 16:19.)

8. Òpin nkan sàn ju ìpilẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ lọ; ati onisuuru ọkàn ju ọlọkan igberaga. (ẹsẹ 1; Owe 14:29; Gal 5:22.)

**Ọgbọn Ọlọrun ṣe iyebíye ju ọrọ̀ ayé lọ.**

9. Máṣe yara ni ọkàn rẹ lati bínú, nitori pe ìbínú ngbe ni àyà aṣiwèrè. (Owe 14:17; Jms 1:19.)

10. Iwọ máṣe wi pe, "Nitori kinni ọjọ iṣaaju ṣe sàn ju wọnyìí lọ?" Nitori pe iwọ kò fi ọgbọ́n beere ni ti eyi.

11. Ọgbọ́n dara gẹ́gẹ́ bi ìní, ati nípasẹ̀ rẹ̀ èrè wa fun awọn ti nri òòrùn. (Owe 8:10,11.)

12. Nitori pe ààbò ni ọgbọn, ani bi owó ti jẹ ààbò: ṣugbọn èrè ìmọ̀ ni pé, ọgbọ́n fi ìyè fún awọn ti o ni i. (Onws 9:18; Owe 3:18; 8:35.)

13. Wo iṣẹ Ọlọrun; nitori pé, tani o lè mu un tọ́ ani èyí ti oun ti ṣe ni wíwọ́? (Onws 3:11: 8:17; 1:15; Isa 14:27.)

14. Ni ọjọ́ alaafia, maa yọ̀, ṣugbọn ni ọjọ iponju, ronú pé, bi Ọlọrun ti da ekinni bẹẹ ni o da ekeji, ni ti ìdí eyi pe ki eniyan máṣe ri nkan ti nbọ lẹ́hìn rẹ̀. (Onws 3:4; Deut 8:5.)

**Ṣe ohun gbogbo ninu ododo Ọlọrun.**

15. Ohun gbogbo ni mo rò ni ọjọ asán mi: otootọ eniyan wa ti o ṣegbe ninu ododo rẹ, ati eniyan buburu wà ti ọjọ rẹ̀ pé ninu ìwà buburu rẹ̀. (Onws 6:12; 8:14.)

16. Iwọ máṣe ṣe ododo àṣelékè; bẹẹ ni ki iwọ máṣe fi ara rẹ ṣe ọlọgbọn àṣelékè: nitori kinni iwọ o ṣe pa ara rẹ run? (Rom 12:3.)

17. Iwọ máṣe ṣe buburu àṣelékè bẹẹ ni ki o má ṣe jẹ òmùgọ̀; nitori kinni

iwọ o ṣe ku ki ọjọ́ rẹ to pé? (Job 15:32; Psm 55:23; Owe 10:27.)

18. O dara ki iwọ di eyi mu; pẹlupẹlu iwọ máṣe yọ ọwọ́ rẹ kuro ninu èyí: nitori ẹni ti o bẹru Ọlọrun ni yoo yọ kuro ninu rẹ̀ gbogbo.

**Nipa ọgbọn Ọlọrun fi ìwà buburu eniyan hàn.**

19. Ọgbọn mu ọlọgbọn lara le ju eniyan alagbara mẹwà lọ ti o wà ni ìlú. (Onws 9:13–18.)

20. Nitori ti kò si olootọ eniyan lori ilẹ̀, ti nṣe rere ti kò si dẹ́ṣẹ̀. (1 A.Ọba 8:46; 2 Kro 6:36; Owe 20:9; Rom 3:23.)

21. Pẹlupẹlu máṣe fiyesi gbogbo ọ̀rọ̀ ti a nsọ; ki iwọ ma baa gbọ ki iranṣẹ rẹ bu ọ.

22. Nitori pé nigba pupọ pẹlu ni àyà rẹ mọ̀ pe iwọ tikararẹ pẹlu ti bú awọn ẹlomiran.

23. Idi gbogbo iwọnyìí ni mo fi ọgbọ́n wá; mo ni, "Emi o gbọn:" ṣugbọn ọ̀nà rẹ̀ jìn si mi. (Rom 1:22.)

24. Eyi ti o jina, ti o si jinlẹ̀ gidigidi, tani o lè wa á ri? (Job 28:12; Rom 11:33.)

25. Mo fi àyà mi si i lati mọ̀, ati lati wadi, lati ṣe afẹri ọgbọ́n ati òye, ati lati mọ iwa buburu wèrè, àní ti wèrè ati ti ìsínwín. (Onws 1:17; 2:12.)

26. Mo sì rí ohun ti o koro ju ikú lọ, àní obinrin ti àyà rẹ jẹ idẹkun ati awọ̀n, ati ọwọ́ rẹ bi ṣẹ́kẹ́ṣẹkẹ̀: ẹnikẹni ti inu Ọlọrun dùn si yoo bọ lọwọ rẹ; ṣugbọn ẹlẹṣẹ ni a o ti ọwọ́ rẹ̀ mu. (Owe 5:3,4; 22:14.)

27. Kiyesi i, èyí ni mo ri, bẹẹ ni oniwaasu wí, ni wiwadi rẹ̀ ni ọkọọkan lati ri òye. (Onws 1:1,2.)

28. Eyi ti ọkàn mi nwa kiri sibẹ, ṣugbọn emi kò ri: ọkunrin kanṣoṣo ninu ẹgbẹrun ni mo ri; ṣugbọn obinrin kan ninu gbogbo awọn wọnyìí, emi kò rí.

29. Kiyesi i, eyi nikanṣoṣo ni mo rí, pé, Ọlọrun ti da eniyan ni iduro ṣinṣin; ṣugbọn wọn ti ṣe afẹri didọgbọn-ibi. (Gen 1:27; 3:6,7.)

ORI 8.

**Pipa ofin ati àṣẹ ọrilẹ-èdè mọ́ jẹ́ ṣíṣe igbọran si aṣẹ Ọlọrun.**

TANI o dabi ọlọgbọn eniyan? Tani o si mọ itumọ nkan? Ọgbọn eniyan mu ojú rẹ dán, ati lile oju rẹ ni a o si yipada. (Owe 4:8,9; Deut 28:50.)

2. Mo gba ọ ni imọran pe, ki iwọ pa ofin ọba mọ́, èyí si ni nitori ibura Ọlọrun. (Eks 17:18.)

3. Máṣe yara lati jade kuro niwaju rẹ̀: máṣe duro nigba ti nkan ba buru nitori ohun ti o wu u ni o nṣe.

4. Nibi ti ọ̀rọ̀ ọba gbe wa, agbara nbẹ nibẹ; tani o si le wi fun un pe, "Kinni iwọ nṣe yìí?" (Job 9:12; Dan 4:35.)

5. Ẹnikẹni ti o pa ofin mọ ki yoo mọ ohun buburu: àyà ọlọgbọn eniyan sì mọ ìgbà ati ọ̀nà.

6. Nitori pé ohun gbogbo ni o ni igba ati ọnà bi o ti lẹ jẹ pe oṣi eniyan pọ ni ori ara rẹ̀. (Onws 3:1,17.)

7. Nitori ti kò mọ ohun ti nbọ: tani o si lè wi fun un bi yoo ti ri. (Owe 24:22; Onws 6:12; 9:12; 10:14.)

8. Kò si eniyan kan ti o lagbara lori ẹmi lati da ẹmi duro; bẹẹ ni kò si lagbara ni ọjọ ikú: ko si irapada ninu ogun naa; bẹẹ ni ìwà buburu kò lè gba awọn oluwa rẹ̀. (Psm 49:6,7; Deut 20:5–8; ẹsẹ 13.)

9. Gbogbo nkan wọnyìí ni mo ri, mo si fiyè si iṣẹ́ gbogbo ti a nṣe labẹ òòrùn: ìgbà kan nbẹ ninu èyí ti ẹnikan nṣe olori ẹnikeji fun ìfarapa rẹ̀. (Onws 4:1; 5:8.)

**Gbogbo awọn alaiwa bi Ọlọrun ni a o da lẹ́jọ́.**

10. Bẹẹ ni mo sì ri isinku eniyan búburú ti o wa ti o si lọ kuro ni ibi mímọ́, a si gbagbe wọn ní ilu naa: asán ni èyí pẹlu.

11. Nitori ti a kò mu idajọ ṣẹ kánkán si iṣẹ buburu, nitori naa àyà awọn ọmọ eniyan mura paapaa lati huwa ibi.

12. Bi ẹlẹṣẹ tilẹ ṣe ibi nigba ọgọrun, ti ọjọ rẹ̀ si gùn, ṣugbọn nitootọ, emi mọ pe yoo dara fun awọn ti o bẹ̀rù Ọlọrun, ti o bẹ̀rù niwaju rẹ̀. (Isa 65:20; Psm 37:11,18,19; Owe 1:32, 33; Isa 3:10,11.)

13. Ṣugbọn ki yoo dara fun eniyan buburu, bẹẹ ni ki yoo fa ọjọ rẹ̀ gun ti o dabi ojiji, nitori ti kò bẹ̀rù niwaju Ọlọrun. (ẹsẹ 8; Isa 3:11; Onws 6:12.)

**Ifẹ Ọlọrun fun eniyan ni pe ki o jẹ ki o sì sìn Ọlọrun ni ayé yìí.**

14. Asán kan nbẹ ti a nṣe ni ayé; ni ti pé, awọn olootọ eniyan kan wà, ti nkan nṣẹlẹ si gẹgẹ bi iṣẹ́ awọn ẹni-buburu; ati pẹlu, awọn eniyan buburu si wà, ti nkan si nṣẹlẹ si wọn gẹ́gẹ́ bi iṣẹ́-olododo: mo ni asán ni eyi pẹlu. (Psm 73:14; Onws 7:15; Job 21:7; Mal 3:15.)

15. Nígbà naa ni mo yin jíjẹ-igbadun, nitori eniyan kò ni ohun rere labẹ òòrùn ju jíjẹ ati mímu, ati ṣiṣe àríyá: nitori eyi ni yoo ba a duro ninu laalaa rẹ ni ọjọ́ ayé rẹ, ti Ọlọrun fi fun un labẹ òòrùn. (Onws 2:24; 3:12,13; 5:18; 9:7.)

**Ọna Ọlọrun kò ṣe rídí fun eniyan.**

16. Nígbà ti mo fi àyà mi si ati mọ ọgbọ́n, ati lati ri ohun ti a ṣe lori ilẹ̀: (ẹnikan saa wa pẹlu ti kò fi ojú rẹ ba oorun ni ọ̀sán ati ni òru. (Onws 1:13,14; 2:23.)

17. Nígbà naa ni mo wo gbogbo iṣẹ́ Ọlọrun, pé eniyan kò le ridi iṣẹ́ ti a nṣe labẹ òòrùn: nitori pé bi eniyan tilẹ gbiyanju ati wadi rẹ̀, síbẹ̀ ki yoo le ri i; ati pẹlupẹlu bi ọlọgbọn eniyan rò lati wadi rẹ̀, síbẹ̀ ki yoo le ridi rẹ̀. (Job 5:9; Onws 3:11; Rom 11:33; Onws 8:7; Psm 73:16.)

## ORI 9.

**Gbogbo eniyan, iba jẹ ẹni-rere tabi ẹni-buburu, ni yoo ku.**

NITORI nkan yìí ni mo rò ni àyà mi, àní lati wadi gbogbo èyí pé, olododo, ati ọlọgbọn, ati iṣẹ wọn, lọwọ Ọlọrun ni o wa: ifẹni ati irira, kò si ẹni ti o mọ, gbogbo èyí wa niwaju wọn. (Deut 33:3; Job 12:10; Psm 119: 109; ẹsẹ 6; Onws 10:14.)

2. Bakan naa ni ohun gbogbo ri fun gbogbo wọn: ohun kan naa ni o nṣe si olododo, ati si ẹni buburu; si eniyan rere, ati si mímọ́ ati si alaìmọ́; si ẹni ti nrubọ, ati si ẹni ti kò rubọ: bi eniyan rere ti ri, bẹẹ ni ẹlẹ́ṣẹ̀; ati ẹni ti nbura bi ẹni ti o bẹru ibura. (Job 9:22; Onws 6:6; 7:2.)

3. Eyí ni ibi ninu ohun gbogbo ti a nṣe labẹ òòrùn, pe iṣẹ kannaa ni si gbogbo wọn: ati pẹlu àyà awọn ọmọ eniyan kun fun ibi, ìsínwín nbẹ ninu wọn nígbà ti wọn wà láàyè, ati lẹhin eyi, wọn a lọ sọdọ awọn òkú. (ẹsẹ 2; Onws 8:11; 1:17.)

4. Nitori pé tani ẹni ti a yàn, ti ireti alààyè wà fun: nitori pé àyè ajá san ju oku kiniun lọ.

5. Nitori alààyè mọ pe awọn yoo ku; ṣugbọn awọn òkú kò mọ ohun kan, bẹẹ ni wọn kò ni èrè mọ́; nitori iranti wọn ti di igbagbe. (Job 14:21; Onws 1:11; 2:16; Psm 88:12; Isa 26:14.)

6. Ifẹ wọn pẹlu, ati irira wọn, ati ilara wọn, o parun nisinsinyìí; bẹẹ ni wọn kò sì ni ìpín mọ lae lae ninu ohun gbogbo ti a nṣe labẹ òòrùn. (Onws 3:22.)

**Maa jẹ igbadun ayé rẹ, nígbà ti o ṣi wa láàyè.**

7. Maa ba tirẹ lọ, maa fi ayọ̀ jẹ ounjẹ rẹ, ki o si maa fi inú dídùn mu ọti-waini rẹ: nitori pe Ọlọrun tẹwọgba iṣẹ rẹ nisinsinyìí. (Onws 8:15.)

8. Jẹ ki aṣọ rẹ maa fún nigba gbogbo; má si jẹ ki orí rẹ ṣe alaini ororo ikunra. (Ifh 3:4; Psm 23:5.)

9. Maa fi ayọ ba aya rẹ gbé ti iwọ fẹ, ni gbogbo ọjọ ayé asán rẹ ti o fi fun ọ labẹ òòrùn: nitori eyi ni ìpín tirẹ ni ayé yìí, ati ninu laalaa ti iwọ ṣe labẹ òòrùn. (Onws 6:12; 7:15.)

10. Ohunkohun ti ọwọ rẹ ri ní ṣiṣe, fi agbara rẹ ṣe e; nitori ti kò si ète, bẹẹ

ni ko si ìmọ̀, tabi ọgbọ́n, ni isà-òkú nibi ti iwọ nrè. (Rom 12:11; Kol 3:23; Isa 38:10.)

**Àkókò kò dúró de ẹnikan.**

11. Mo pada, mo si ri labẹ òòrùn, pe iré-ìjẹ kì i ṣe ti ẹni ti o yára bẹẹ ni ogun ki i ṣe ti alagbara, bẹẹ ni ounjẹ kì i ṣe ti ọlọgbọn, bẹẹ ni ọrọ̀ ki i ṣe ti ẹni òye, bẹẹ ni ojurere ki i ṣe ti ọlọgbọn-inú; ṣugbọn ìgbà ati èṣì nṣe si gbogbo wọn. (Amos 2:14,15; Deut 8:17,18; 1 Sam 6:9.)

12. Nitori pe eniyan pẹlu kò mọ ìgbà tirẹ; bi ẹja ti a mu ninu àwọ̀n buburu, ati bi ẹyẹ ti a mú ninu okùn; bẹẹ ni a ndẹ awọn ọmọ eniyan nigba buburu, nigba ti o ṣubu lù wọn lojiji. (Onws 8:7; Owe 29:6; Isa 24:18; Luk 21:34, 35.)

**Ọgbọ́n sàn ju agbara eniyan lọ.**

13. Ọgbọ́n yìí ni mo ri pẹlu labẹ òòrùn, o si dabi ẹni pé o tobi fun mi.

14. Ilu kekere kan wà, ati eniyan diẹ ninu rẹ̀; ọba nlá kan si gbe ogun tọ̀ ọ́ lọ, o si doti i, o si mọ ilé-ìṣọ́ ti o tobi ti i.

15. A si ri ọkunrin talaka ọlọgbọn ninu rẹ̀, oun si fi ọgbọ́n rẹ gba ilu naa silẹ; ṣugbọn kò si ẹnikan ti o ranti ọkunrin talaka naa. (Onws 4:13; 2:16; 8:10.)

16. Nígbà naa ni mo wi pe, Ọgbọ́n sàn ju agbara lọ; ṣugbọn a kẹgan ọgbọn ọkunrin talaka naa, ohùn rẹ̀ kò si to òkè. (Owe 21:22; Onws 7:19.)

17. A ngbọ ọ̀rọ̀ ọlọgbọn eniyan ni pẹlẹ ju igbe ẹni ti o jẹ olori ninu awọn aṣiwere. (Onws 7:5; 10:12.)

18. Ọgbọ́n sàn ju ohun-elo ogun: ṣugbọn ẹlẹṣẹ kan yoo ba ohun didara pupọ jẹ. (ẹsẹ 16; Jos 7:1,11,12.)

ORI 10.

**Ọgbọ́n ni nranilọwọ ṣugbọn ìwà were ni npanilara.**

OKÚ eṣinṣin mu òróró-ikunra alápòlù bàjẹ́, ti o si nrun òórùn buburu: bẹẹ ni wèrè diẹ wuwo ju ọgbọn ati ọlá lọ.

2. Àyà ọlọgbọn nmu un tẹsi ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀; ṣugbọn àyà aṣiwere si òsì rẹ̀.

3. Ati pẹlu nigba ti ẹni ti o ṣiwere ba nrin ni ọ̀nà, ọgbọn rẹ̀ a fò lọ, oun a si wi fun olukuluku eniyan pé aṣiwere ni oun. (Owe 13:16; 18:2.)

4. Bi ọkàn ijoye ba rú si ọ, máṣe fi ipò rẹ silẹ̀; nitori pé itumba a maa tu ẹṣẹ nla. (Onws 8:3; 1 Sam 25:24–33; Owe 25:15.)

5. Buburu kan nbẹ ti mo ri labẹ òòrùn, bi iṣina ti o ti ọdọ awọn ijoye wa. (Onws 5:6.)

6. A gbe aṣiwere sipo olá, awọn ọlọ́rọ̀ si jokòó nipo ẹ̀hìn. (Est 3:1.)

7. Mo ri awọn ọmọ-ọdọ lori ẹṣin, ati awọn ọmọ-alade nrin bi ọmọ-ọdọ ni ilẹ̀. (Owe 19:10; Est 6:8.)

8. Ẹni ti o wa ihò ni yoo bọ sinu rẹ̀; ati ẹni ti o si nja wọ inú ọgba, ejò ni yoo si bu u ṣan. (Psm 7:15; Owe 26:27.)

9. Ẹni ti o nyi okuta yoo si ti ipá rẹ ni ipalara; ati ẹni ti o si nla igi ni yoo si ti ipa rẹ wewu.

10. Bi irin ba kújú ti a kò si pọ́n oju rẹ̀, njẹ ki o fi agbara si i; ṣugbọn ọgbọ́n ni nran ni lọ́wọ́ lati ṣe aṣe-yọri.

11. Nitootọ bi ejo ba bu ni ṣán ki a to tujú fun un; anfani kò si fun olùtùjú. (Psm 58:4,5; Jer 8:17.)

**Ọ̀rọ̀ asán eniyan mu ìpalára wa fun un.**

12. Ọ̀rọ̀ ẹnu ọlọgbọn ní oore-ọ̀fẹ́; ṣugbọn ètè omugọ ni yoo gbe ara rẹ mì. (Owe 10:32; Luk 4:22; Owe 10:14; 18:7.)

13. Ipilẹṣẹ ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ ni wèrè: ati òpin ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ ni ìsínwín buburu. (Onws 7:25.)

14. Aṣiwère pẹlu kún fún ọ̀rọ̀ pupọ: eniyan kò lè sọ ohun ti yoo ṣe; ati ohun ti yoo wa lẹhin rẹ̀, tani o lè wi fun un? (Owe 15:2; Onws 3:22; 6:12; 8:7.)

15. Làálàá aṣiwere da olukuluku wọn ni agara, nitori ti kò mọ̀ bi a ti nlọ si ilu.

**Maa şe ohun gbogbo ni àkókò ti o yẹ.**

16. Ègbé ni fun ọ, iwọ ilẹ, nigba ti ọba rẹ ba şe ọmọde, ti awọn ọmọ-alade rẹ njẹun ni kùtùkùtù. (Isa 3:4, 5,12; 5:11.)

17. Ibukun ni fun ọ, iwọ ilẹ, nigba ti ọba rẹ ba jẹ ọmọ ọlọla, ti awọn ọmọ-alade rẹ njẹun ni akoko ti o yẹ, fun ilera, ti ki i si şe fun imọtipara! (Owe 31:4; Isa 5:11.)

18. Nipa ìjáfara igi ilé a wúlẹ́; ati nipa ọlẹ ọwọ́, ile a si maa jò. (Owe 24:30–34.)

19. Ohun-ẹrín ni a nsàsè fún, bẹẹ ni ọti-waini ni nmú inú alàáyè dùn: owó si ni idáhùn ohun gbogbo. (Psm 105:15; Onws 7:12.)

20. Máşe bú ọba, ki o má si şe ninu èrò rẹ rara; máşe bú ọlọ́rọ̀ ni iyẹwu rẹ nitori pé ẹyẹ ojú-ọrun yoo gbe ohùn naa lọ, ohun ti o ni ìyẹ́-apa yoo si sọ ọ̀ràn naa. (Eks 22:28; A.A. 23:5; 2 A.Ọba 6:12; Luk 12:3.)

## ORI 11.

**Şe işẹ aanu rẹ lati inu ifẹ Ọlọrun wá; èyí yoo mu èrè púpọ̀ wa fun ọ.**

DA ounjẹ rẹ si oju omi; nitori ti iwọ o ri i lẹ́hìn ọjọ pupọ. (Isa 32:20; Deut 15:10; Owe 19:17; Matt 10:42; 2 Kor 9:8; Gal 6:9,10; Heb 6:10.)

2. Fi ìpín fun meje ati fun mẹjọ pẹlu, nitori ti iwọ kò mọ ibi ti yoo wà láyé. (Psm 112:9; Luk 6:30; 1 Tim 6:18,19; Onws 12:1.)

3. Bi ìkúukùu awọsanma ba kun fun òjò, wọn a si tu da si ayé: bi igi ba si wo siha gusu tabi siha ariwa, nibi ti igi naa gbe şubu sí, nibẹ ni yoo si maa gbé.

4. Ẹni ti o nkiyesi afẹfẹ ki yoo fúnrúgbìn; ati ẹni ti o si nwoju ìkúukùu awọsanma ki yoo şe ìkórè.

5. Bi iwọ kò ti mọ ipa-ọna afẹ́fẹ́, tabi bi egungun ti ndàgbà ninu aboyun: àní bẹẹ ni iwọ kò lè mọ işẹ Ọlọrun ti nşe ohun gbogbo. (Jhn 3:8; Psm 139:14,15.)

6. Ni kutukutu, fún irúgbìn rẹ, ati ni àşálẹ́ máşe da ọwọ́ rẹ dúró: nitori ti iwọ kò mọ eyi ti yoo şe rere, yala eyi tabi eyiyií, tabi bi awọn mejeji yoo dara bakan naa. (Onws 9:10.)

7. Nitootọ imọlẹ dun, ati ohun didara ni fún oju lati wo òòrùn. (Onws 7:11.)

8. Bi eniyan ba gbe ọpọlọpọ ọdún, jẹki oun o yọ̀ ninu gbogbo wọn, şugbọn jẹ ki o ranti pé ọjọ okunkun yoo pọ̀. Ohun gbogbo ti nbọ, asán ni. (Onws 9:7; 12:1.)

**Ìşìnà ni fun ọ̀dọ́ lati maa rìn ninu ifẹ ara wọn.**

9. Maa yọ, iwọ ọ̀dọ́mọdé ninu èwe rẹ; si jẹ ki ọkàn rẹ mu ọ láraya ni ewè rẹ, si maa rìn nipa ọ̀nà ọkàn rẹ ati nipa ìrí ojú rẹ; şugbọn mọ eyi pe, nitori nkan wọnyií Ọlọrun yoo mu ọ wa si idajọ. (Onws 2:10; Num 15:39; Onws 3:17; 12:14; Rom 14:10.)

10. Nitori naa mu ibanujẹ kuro ni àyà rẹ, si mu ibi kuro ni ara rẹ: nitori pe asán ni ìgbà-èwe ati ìbẹ̀rẹ̀ ọjọ́ ayé. (2 Kor 7:1; 2 Tim 2:22.)

## ORI 12.

**A ni lati gbe igbe ayé wa pẹlu ibẹru Ọlọrun.**

RANTI ẹlẹda rẹ nisinsinyií ni ọjọ èwe rẹ, nigba ti ọjọ́ ibi koi ti de, ati ti ọdún koi ti sunmọ etílé, nígbà ti iwọ o wi pe, "Emi kò ni inú dídùn ninu wọn." (Psm 63:6; 119:55; Onws 11:8; 2 San 19:35.)

2. Nigba ti òòrùn, tabi imọlẹ, tabi òşùpá tabi awọn irawọ koi ti şu òkùnkùn, ati ti ìkúukùu awọsanma koi ti padà lẹ́hìn òjò:

3. Ni ọjọ ti awọn oluşọ ile yoo wárìrì, ati ti awọn ọkunrin alagbara yoo tẹri wọn ba, awọn òòlọ̀ yoo si dákẹ́ nitori ti wọn kò to nkan, ati awọn ti nwode loju ferese yoo şu òkùnkùn,

4. Ti ilẹkun yoo si tì ni ìgboro, nigba ti iro ọlọ yoo rẹlẹ̀, ti ẹnikan yoo si dide ni ohùn kike ẹyẹ, ati ti a o rẹ gbogbo

awọn ọmọbinrin olórin silẹ. (Jer 25:10; 2 Sam 19:35.)

5. Ati pẹlu ti wọn o bẹ̀rù ibi ti o ga, ti ìwárìrì yoo si wa ni ọ̀nà, ati ti igi almọndi yoo tanna, ti ẹlẹ́ngà yoo di ẹrù, ti ifẹ yoo si ṣá: nitori ti ọkunrin nlọ si ile rẹ̀ ayérayé, awọn aṣọ̀fọ̀ yoo si maa yide kakiri. (Job 17:13; Jer 9:17.)

6. Tabi ki okùn fàdákà to ja, tabi ki ọpọ́n wura tó fọ́, tabi ki iṣa to fọ nibi isun, tabi ki kẹkẹ to kán nibi kọnga,

7. Nigba naa ni erùpẹ̀ yoo pada si ilẹ̀ bi o ti wà ri, ẹmi yoo si pada tọ Ọlọrun ti o fi i fun ni. (Gen 3:19; Job 34:15; Psm 90:3; Job 34:14; Isa 57:16; Sek 12:1.)

8. Asán ninu asán, oniwaasu wi pe, gbogbo rẹ asán ni. (Onws 1:2.)

**Ọgbọn Ọlọrun ni o mu ki eniyan ri ìdí ohun ti o jinlẹ̀.**

9. Ati pẹlu, nitori Oniwaasu naa gbọn, o si nkọ awọn eniyan ni ìmọ̀ pẹlu; nitootọ o ṣe akiyesi daradara, o si wadi, o si fi owe pupọ lélẹ̀ ni ẹsẹsẹ. (1 A.Ọba 4:32.)

10. Oniwasu naa wadi lati ri ọ̀rọ̀ dídùn, pẹlu ni ìdúró ṣinṣin, o kọ ọ̀rọ̀ otitọ. (Owe 10:32; 22:20,21.)

**Ṣiṣe iyebiye ọ̀rọ̀ oniwaasu.**

11. Ọrọ ọlọgbọn dabi ẹ̀gún, ati gẹgẹ bi ìṣọ́ ti a kàn, bẹẹ ni akojọ ọ̀rọ̀ ti a nfi fun ni lati ọwọ oluṣọ-agutan kan wa. (Onws 7:5; A.A. 2:37; Esra 9:8; Isa 22:23.)

12. Ati ṣiwaju, lati inu èyí, ọmọ mi, gba imọran: ninu kikọ iwe pupọ, opin ko si; ati iwe kika pipọ ni àárẹ̀ ara.

**Oniwaasu fẹ ki a mọ̀ pe a o mu gbogbo iṣẹ wá si ìdájọ́.**

13. Opin gbogbo ọrọ naa ti a gbọ ni pe: Bẹru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori èyí ni fun gbogbo eniyan. (Deut 4:2; Onws 8:5; Mika 6:8.)

14. Nitori pe Ọlọrun yoo mu olukuluku iṣẹ wa sinu ìdájọ́, ati olukuluku ohun ìkọ̀kọ̀, ibaa ṣe rere, ibaa ṣe buburu. (Matt 10:26; 12:36; 1 Kor 4:5.)

22

# ORIN SOLOMỌNI

**(B.C. 1014)**

ORI 1.

**Àkọlé.**

Orin awọn orin tí i ṣe ti Solomoni. (1 A.Ọba 4:32.)

**Ọkọ nreti Olùfẹ́ rẹ̀.**

2. Jẹ ki ó fi ìfẹnukonu ẹnu rẹ̀ kò mi ní ẹnu nitori ifẹ́ rẹ̀ sàn ju ọtí-waini lọ. (O.Sol. 4:10.)

3. Nitori ti oorun ìkunra rere rẹ̀, orúkọ rẹ̀ dabi ìkunra tí a tú jáde, nitori naa ni àwọn wúndíá ṣe fẹ́ ọ. (O.Sol. 4:10; Onws 7:1.)

4. Fà mi, àwa o sare tọ̀ ọ́: ọba ti mú mi wá sinu iyàrá rẹ̀: awa o yọ̀, inu wa yoo si dùn si ọ, awa yoo ranti ìfẹ́ rẹ ju ọti-waini lọ; wọn fẹ ọ nitootọ. (Psm 45:14,15.)

5. Emi dúdú, ṣugbọn mo ní ẹwà, Ẹyin ọmọbinrin Jerusalẹmu, bi àwọn àgọ́ Kédárì, bi àwọn aṣọ-tita Solomoni. (O.Sol. 2:14; 4:3; 2:7; 5:8.)

6. Ma ṣe wò mi, nitori pé mo dúdú, nitori pé òòrùn ti bojuwo mi: awọn ọmọ ìyá mi binu si mi; wọn fi mi ṣe oluṣọ ọgbà-àjàrà; ṣugbọn ọgbà-àjàrà tèmi ni èmi kò tọju. (Psm 69:8; O.Sol. 8:11.)

7. Wi fun mi, Ìwọ ẹni tí ọkàn mí fẹ́, ni ibi ti iwọ nṣọ́ agutan; ni ibi ti iwọ